# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

## OSÙ KEJÌLÁ, ỌDÚN 2021

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́ ati**

**ISÌN IFÒRÒRÓYÀN**

## OṢÙ KEJILÁ 2021 – DÍDÒJÚKỌ ÌRÚNÚ ÀWỌN ẸMÍ JẸRAN-JẸRAN ÀTI MÙJẸ̀-MÙJẸ̀ (3)

7:00 am – 7:05 am Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀
7:05 am – 7:20am Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn
7:20 am – 7:35 am Ijẹ́rì
7:35 am – 7:45 am Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdáṣe
7:45 a m – 8:45 am Iṣẹ́ Ìránṣẹ́
8:45 am - 9:00 am Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé

**Orin ibẹ̀rẹ̀**

1. Gbọ́ ìró lí òpópó ayé,
Bí ti igbì omi òkun,
Tí nfi agbára rẹ ru s'ókè
T'ó sì nkọlù èbúté.

Egbe:
Gbọ́ bo ẹṣẹ̀ ọmọ ogun
Bí wọn tí nrìn lọ lí ọnà ná,
Arẹ́ mú wọn fún 'ṣẹ́ àti'ìrìn àjò
Àti ìjà kíkorò
Ṣùgbọ́n wọn gbàgbọ́, wọ́n tẹjúmọ́
Ọ̀nà ná t'áwọn mímọ́ ti nrìn,
Bí wọ́n ti nlọ ní 'gbàgbọ́
Wọ́n ndàgbà n'nù Ọlọ́run Alàyè.

2. Wọ́n ntẹsìwájú pẹ̀lú 'gbàgbọ́
Tí ẹ̀kọ́kẹ́kọ̀ kò le mì;
Wọ́n gbàgbọ́ pé ọ̀rọ̀ Ọlọ́run
Lè pèsè f'áìní gbogbo.

3. Dàpọ̀ mọ́ wọn, àyè wà síbẹ̀
Dúró de 'bùkún Ọlọ́run:
Òun ni 'rètí gbogbo agbàyé
Láti ṣiṣẹ́ odòdo.

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Gbogbo àsọtẹ́lẹ̀ òdì, tó lódì sí ayé mi yóò padà sọ́dọ̀ ẹni tó ran lónìí, nípa agbára t'ówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
2. Nipá dídá orúkọ Jésù Kristì Olúwa lónìí, gbogbo ètò òpin ọdún sátánì fún emi ati ìdílé mi yóò ta padà, ní orúkọ Jésù.
3. Bí n ó ṣè kópa nínú ètò tonìí, mo gba agbára láti gba gbogbo ibùkún mi tó ṣẹ́kù nínú ọdún yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Nínú ètò yìí, Olúwa yóò jẹ́ kí àwọn èrò alàjá ọ̀tun sọjí nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
5. Nínú ètò tonìí, Olúwa yóò fún mi ní ohun tímo nílò láti fi ṣaṣèyọrí lọ́dún tó n bọ̀, ní orúkọ Jésù.
6. Lónìí, nípa agbára t'ówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ògo mi yóò farahàn, gbogbo òkè iṣòro mi yóò poòrá, ní orúkọ Jésù.
7. Lónìí, Olúwa yóò dáhùn gbogbo àdúrà mi gẹ́gẹ́ bí Ó ti dáhùn àwọn ẹ̀bẹ̀ Jábésì, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ìwọ agbára tó wà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, dá gbogbo ibùkún mi tímo pàdánù padà fún mi, ní orúkọ Jésù.
4. Ìwọ agbára tó wà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, kókìkí ògo mi, ní orúkọ Jésù.
5. Agbára tó wà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù yóò ṣe àṣepé iṣẹ́ ìgbéga mi lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ibẹ̀wò tí wọ́n ṣe kí wọ́n tó lóyún mi, tó n dàmí láàmú báyìí, gba ìparun nípa agbára tówa nínù ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.

7. Àrá Olúwa, pa gbogbo igi àti ewé búburú run, tí wọ́n bẹ̀wò nítorí mi, tó n fa idárogún nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**Ìsáíàh 40:29:** Ó nfi agbára fún alãrẹ̀; ó sì fi agbára kún àwọn tí kò ní ipá.

**Fílíppì 4:19:** Ṣùgbọ́n Ọlọ́run mi yóò pèsè ní kíkún fún gbogbo aìní nyín, gẹ́gẹ́ bí ọrọ̀ Rẹ̀ nínú ògo nínú Krístì Jésù.

**Orin Dáfídì 107:20:** Ó rán ọ̀rọ rẹ̀, ó sì mú wọn lára dá, ó sì gbà wọ́n kúrò nínú ìparun wọn.

**Orin Dáfídì 147:3:** Ó mú àwọn onírora àyà lára dá: o dí ọgbẹ́ wọn:

**Ìsáíàh 57:18-19:** Mo ti rí ọ̀nà rẹ̀, èmi ó sì mú ú lí ara dá: èmi ó sì tọ́ ọ́ pẹ̀lú, èmi ó sì mú itùnú padà fún ú wá, àti fún àwọn aṣọ̀fọ̀ rẹ̀. Èmi lí ó dá èso ètè; Alàfíà, alàfíà fún ẹnití ó jìnà réré, àti fún ẹnití ó wà nítòsí, ní Olúwa wí; èmi ó sì mú ú lí ara dá.

**Rómù 8:37:** Ṣùgbọ́n nínú gbogbo nkan wọ̀nyí àwa jù ẹnití o ṣẹ́gun lọ nípa ẹnití ó fẹ́ wa.

**Máttéù 9:21:** Nítorí ó wí nínú ara rẹ̀ pé, Bí mo bá ṣá à lè fi ọwọ́ kan aṣọ rẹ̀, ara mi ó dà.

**Deuterónómì 7:15:** OLÚWA yóò sì gbà àrùn gbogbo kúrò lọ́dọ̀ rẹ, kì yóò sì fi ọ̀kan nínú àrùn búburú Égíptì, tí ìwọ mọ̀, sí ọ lára, ṣùgbọ́n òn o fi wọ́n lé ara gbogbo àwọn tí ó kórira rẹ.

**Ìsáíàh 58:8:** Nígbàná ni ìmọ́lẹ̀ rẹ yóò bẹ́ jáde bí òwúrọ̀, ìlera rẹ yóò sọ jáde kánkán: òdodo rẹ yóò sì lọ ṣájú rẹ; ògo Olúwa yóò kó ọ jọ.

**Jeremíàh 17:14:** Wò mí sàn, Olúwa, èmi ó sì sàn! gbà mí là, èmi ó sì là, nítorí ìwọ ni ìyìn mi!